**ỌJATITUN**

Iwe Iṣegun Aje 4/6d
Iwe Mọsẹ 4/6d
Iṣẹdalẹ Yoruba 4/6d
Turari iṣegun Aje 10/6d
Iwe Ala nla 7/6d
Kọ iwe si
Manager,
SHOYINKA,
6, Ojo Road,
Odu-Abọrẹ, Mushin.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**OWE**

Iku pa egungun, ilẹ gbe oro mi i, ṣanpọnna yinbọn je, ẹlẹrugun ṣango lu magun o kụ, Babalawo ti iba wadi ọran na, Ogun ti mu re Idahọmy, awọn Oriṣa ti o ng roni lẹro ṣẹ ntan nile aiye.

VOL. VI No. 350 MONDAY OCTOBER 1 — OCTOBER 7 1962 KỌBỌ MEJI (2d)

# OBINRIN KAN JI ỌMỌ ỌJỌ MARUN GBE !

IKẸJA:- Ogunlọgọ awọn obinrin bẹrẹsi lọ bosi nwọn si nsare kọ lu ara wọn tele obinrin abilekọ kan, ti orukọ rẹ njẹ, Olufunmilayọ Duroshomọ bọ wa si Tẹṣan Ọlọpa Mushin ni ọsan ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu kẹsan odun yi, wipe o ji ọmọ tuntun kan gbe.



ATỌKẸ YINUSA
*IYA ỌMỌ*

Nigbati nwọn mu obinrin na, Olufunmilayọ Duroshọmọ de ọdọ awọn Ọlọpa, awọn Ọlọpa ṣe alaye wipe, jiji ni Olufunmilayọ ji ọmọ ọjọ marun ti o gbe pọn wa si Tẹṣan na gbe mọ Iya-ọmọ tuntun na, Atọkẹ Yinusa lọwọ ni ile igbẹbi awọn abiyamọ ti o wa ni Ikẹja.

Ọlọpa tun ṣe alaye siwaju si i wipe ọkọ obinrin ajọmọgbe na, ti orukọ rẹ njẹ A. Duroshọmọ ni o mu ẹsun wa si ọdọ awọn Ọlọpa wipe lojiji ni on ri Iyawo on na Funmilayọ Duroshọmọ ti ko loyun fun on tẹlẹtẹlẹ, ti o si gbe ọmọ tuntun na wa ba on nile wipe on ti bimọ tuntun, o ni ọrọ na si ya on lẹnu pupọ ni on ba fi wa sọ fun awọn Ọlọpa.

Alaye ti awọn Ọlọpa ṣe nipa ọmọ na ni pe, obinrin kan, Iyaafin Atọkẹ Yinusa, ti o ngbe Tabọntabọn ni agbegbe Agege ni o wa bi ọmọ na sinu ile-igbẹbi awọn abiyamọ ni ile-iwosan nla Ikẹja ni nkan bi ọjọ marun sẹhin, nigbati o si di alẹ ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ogunjọ oṣu yi, ni Iya ọmọ na ba lọ si baluwẹ, nigbati o pada de ni o ba fẹ ọmọ rẹ ku lori itẹ rẹ, o si fi igbe ta.



OLUFUNMILAYỌ DUROṢHỌMỌ
*AJỌ'MỌGBE*

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn Olutọju alaisan ati Ọga Ile-igbẹbi ba bẹrẹsi ṣe wahala lati wa ẹniti o gbe ọmọ na ri, nigbati nwọn ko si rii lẹhin ọpọlọpọ wakati ni nwọn ba lọ fi ẹjọ sun awọn Ọlọpa wipe, ẹnikan ji ọmọ gbe ni Ile iwosan.

Bi nwọn ba ti ṣẹjọ Olufunmilayọ ajọmọgbe na si, ẹ o tun maa gbọ ninu iwe Irohin Imọlẹ ti ọsẹ ti mbọ o.

## Ẹni tanwi, o de



ỌGBẸNI ADEKUNLE ỌJỌRA

Gbogbo enia ni o bẹrẹsi yọ ṣẹṣẹ ni ile-iṣẹ Onisowo U. A. C. lẹnu lọlọ yi nigbati Ọga wọn, Ọgbẹni Adekunle Ọjọra, ti iṣe alakoso iṣẹ ilosi ni Ipinlẹ Iwọ Oorun Naijiria de si ile-iṣẹ lati wa gba ipo Ọgbẹni Denis Parker.

Awọn enia na nyọ nitoripe Ọgbẹni Ọjọra ni ekini ninu ọmọ Naijiria ti yio kọkọ wa ni ipo yi. Awọn Oyinbo ni nwọn ti nwa ni aye na.

Awa Oniwe IROHIN IMỌLẸ ki gbogbo awọn osiṣẹ ile-iṣẹ U. A. C. ku amọjuba. Bẹni a si tun ki Ọgbeni Ọjọra ku ori re. Iwaju lọpa ẹbiti re si, ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o.

## Ọlọpa ri ori enia nile ọkunrin kan

UMUAHIA:- Awọn Ọlọpa mu ọdaran onisegun kan, Okerie Obi ti o ngbe abule Akpuoha ni agbegbe Umuahia wa siwaju adajọ fun ẹsun pe awọn ri ibọn ni ile rẹ ati ori ọmọ enia ni ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu kẹsan ọdun yi.

Adajọ ti yẹ gbigbọ ẹjọ na sigbamiran.

# IWE SI OLOTU

## Irohin Imọlẹ ati Imọlẹ owurọ ti jẹ?

Olotu/ Kini iyatọ larin Imole Owurọ ati Irohin Imole? Nwọn ni ẹnikan na lo si Imọlẹ Owurọ ati Irohin Imọlẹ ati wi ẹ ẹnyin si ẹ ntẹ mejeji.

Inu wa yio dun ti ẹ ba le ṣe alaye fun wa lori ọrọ yi Ọrọ na ti da ija silẹ larin emi ati ẹgbọn mi, ti a ko si ti pari ija na pelu Mo si ti ṣe ileri wipe, ti o ba jẹ wipe ẹlomiran lo ni Iwe Irohin Imọlẹ nko ni ka a mọ.

Emi ni
RAIMI ADENIRAN
EBUTE—METTA

## Akiyesi

IROHIN IMOLE ati IMỌLẸ OWURỌ ko ni nkankan ba ra wọn ṣe, awa kọ ni a ntẹ Imọlẹ Owurọ

Nigbati Iwe na jade, o ya wa lẹnu lopolọpọ lati ri i wipe oruko iwe na IMỌLẸ papọmọ tiwa ati paapa julọ Esin ọrọ wa IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA, tun jẹ bakanna lafiko si iyatọ laarin mejeji.

Bẹni IWE IROHIN IMỌLẸ ti berẹsi jade lati ọdun karun sẹhin (1957) a si gba Iwe-aṣẹ ni Ile-aṣẹ Minista Alamojuto Eto iṣẹ abe'le.

Lẹsẹkẹsẹ ti iwe na jade ni a ti kọ iwe si wọn fun atunṣe, ṣugbọn a ko ti i ri iyipada na. Ti nwọn ko ba si ṣe iyipada na laipẹ, ao fi ọrọ na le awọn Alaṣẹ Ijọba lọwọ fun ayewo

Ẹ ku afiyesi o. Ajinde ara yio ma a jẹ o.

IROHIN IMỌLẸ ati IMỌLẸ OWURỌ ki iṣe ọkanna o.

*OLOTU*

## Ẹ ku ipalẹmọ o

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati ke si gbogbo Ọmọ Igbaja, nile, loko pe, nwon ku ipalẹmọ ti Mosalasi tuntun ti a fẹ kọ si ilu wa IGBAJA.

Olọrun ko ni jẹ ki o rẹ o y i n, yio si ba wa pari iṣẹ na layọ ati alafia.

Olotu mo dupe aye ti ẹ gba mi

Emi ni
J. K. OWOLABI
IGBAJA-ILỌRIN

## Ẹ fun wa ni Ẹr-ọomi

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati kesi awọn Alaṣẹ Ijọba Igbotako ati paapa julọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun pe ki nwọn fun wa ni ẹrọ-omi ati ina elentiriki ni Ilu wa IGBOTAKO.

Ki awa na le ma a jẹ anfani ti awọn ilu miran nje ni ipinlẹ na.

Olotu mo dupe aye ti ẹ gba mi o.

Emi ni
JOSHUA M. KUNLERE
GBOTAKO

## Oju ọna Okeya nfẹ Ọda

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati ke si awọn Alaṣẹ Ijọba Okeya, ki nwon jọwọ ba wa da Ọda si oju-ọna ilu wa Okeya. Ọna na ko dara le rara lati Alaṣẹ-Ino, Okeya, ati Igbaja de Oke-Ode. O lere ma jẹki moto ati kẹkẹ le rin dada lọna.

Bẹni awọn ọmọ Okeya ki i fi owo ori jafara lodọdun. Ao ṣ'ope bi Ijọba tere na ba le ṣe e fun wa ki awa na le ni anfani ti awọn ilu miran ni, ni ipinlẹ na.

Olotu mo dupe aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
SAIDU GIWA BALE
OKEYA-OFFA

## Owo Ikore ti jẹ?

Jọwọ gba mi laye lati kesi awọn Olukọ ki nwọn fi opin si iwa pe ki nwọn o ma a le ọmọ jade ni ile-iwe nitori owo ikore?

Mo si tun bẹ ijọba, ki nwọn gba wa kalẹ lọwọ awọn Oga ile iwe ti nwon nsọ wipe awọn ọmọ ko ni ṣe idanwo afi bi nwon ba san ṣile mewa (10/-) owo ikore.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
COMFORT MỌRENIKẸ
YABA

## Ẹ la eyi ye mi

Olotu/

Jọwọ gba mi laye lati se ibere yi lọwọ awọn Onkawe wa.

Ibere na ni yi:—

Nje o yẹ ki Ọmọ sa fi iwaso Baba rẹ lopo. Nigbati Baba rẹ ku tan?

Ẹ ku iṣẹ o

Emi ni
ALUFA D. A. OPẸLOYẸRU
EKO.

## Idahun si ibere Saka

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati da Ọgbeni Saka A Olowonilara lohun ibere rẹ ti o jade ni 17/9/62, ti o sọ pe iya kan ku, o si fi a w ọ n ọmọ sile aiye lọ. Ṣugbọn bi o ti ku ni awọn ẹbi rẹ ti ko gbogbo dukia rẹ. Nigbati nwọn pari oko, Onile wọn pe awọn ọmọ oku lati wa san gbese ti iya wọn jẹ ki o to ku.

Gẹgẹbi ero ọkan t'emi awọn ẹbi lo yẹ ki o san gbese na, nitori wipe awọn ẹbi lo ko gbogbo dukia I y a a w ọ n ọmọ na. Nitorina awọn ọmọ ko ni ẹtọ lati san gbese na.

Olotu, mo dupẹ aye ti ẹ gba mi. Ọkọ Ọba ko ni sa nyin lẹsẹ o.

Emi ni
OSENI A. ABIDOYE
EKO

# Obinrin kan ji Adiẹ meji

GBOGBO ero kotu lo pa lọlọ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu ti o kọja yi' nigbati awọn Olọpa mu gbajumọ Ọdaran obinrin kan, Muniratu Asaba wa si waju adajọ kotu fun ẹsun Olè jija.

Olopa ti o ba ọdaran na wijọ ṣe alaye fun kotu pe, nigbati ọdaran na lọ si ọja Ọba ni o ba lọ si iṣọ alaḍiẹ ti o ti debe ti o ti tọwọ bọ agọ adiẹ Iyaafin Latundun A j i k ẹ o si mu adiẹ meji ti iye owo wọn jẹ sile mejeji o (7/6d). Bi o ti pẹhin da, ti o ni fẹ m a a lọ ni meji na mu u.

Nigbati adajọ bere ọrọ lọwọ ọdaran na, ti o si gba wipe o ni iṣẹ, ni adajọ ba ni ki o lọ fi awọn osu mẹta jura.

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TONIKI TITUN TI OSESE DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TỌNIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN EGBOGI AGBALAGBA ỌKUNRIN ATI OBINRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe hanhanhan ti awọn Jamani li nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pelu wọn to jẹlẹ, Lẹhin igbana a ko ti irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju be yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa tọrọ si awọn Ogbologbo Dokita wa ni ilu Jamani pe ki wọn se iwadi awọn elegbogi "Dynaamiren" bi wọn ba si rẹbẹ laiye Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ ati pe egbogi na [illegible] lodọ wọn wa pẹl 'nEyi mu inu wa dun pupọ julọ nitori pe awọn Ombara wa mọ daju wipe kosi ẹyanu [illegible] gbogbo egbogi wa rara, Egbegbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn [illegible] eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣe ti o ko ba jeun daradara, tabi ki o ma le sun de bi kọn lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arọ Ẹ-ẹmi (breath) inu ko ba sunle daradara to nitori pe iṣẹ tabi wahala [illegible] "NJE" fun wọn ni ailera gbogbo wọnyi ti [illegible] (age) [illegible] ti koja Ogbọn ọdun lọ si dede adọrin tabi [illegible] mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti [illegible] ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a [illegible] jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio [illegible] nigba kugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pelu.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 TINUBU STREET, LAGOS PHONE: 20278.

Waterloo Medicine Stores,
8, Pimchurch Street. Lagos,
Phone: 22878 Nigerian, (Oja ita Faji)

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET, YABA: PHONE 22878

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO

Odo ni, on ko gba E w u r ẹ, bẹni on ko gba Aguntan, kosi en ti on Odo yio gba ninu ohun ti ẹnu nje, bikoṣe Ọmọ kan ṣoṣo ti Moremi bi ti oruko rẹ nje "OLUOROGBO".

Ni kukuru, ni alaiko b'oju wo ẹhin, Moremi ki ọmọ kanna ṣoṣo to bi ninu aiye rẹ mọlẹ, o lọ fi rubọ fun Odo-Esinmirin, ki irọrun le kari gbogbo ọmọ Ifẹ. Nigbati Ifẹ gbọ ṣe iyanu n l a ti Mọremi fi ọmọ rẹ kanna ṣe, ibanujẹ de ba gbogbo ọmọ Ifẹ, ti o fi ṣe ọfọ ọmọ na.

Ọfọ ọmọ Mọremi yi ni Ifẹ ma nṣe, eyi ti ki nje ki nwọn o ma ju Ilu bi nwọn ba nṣe ọdun ti wọn fi nṣe iranti Mọremi lọdọdun titi di oni oloni yi.

IFẸ NṢE IRANTI ỌMỌ MỌREMI

Nipa ohun ti Mọremi ṣe yi ni o mu ki gbogbo ọmọ-Ifẹ ni'le lo'ko ati nilu okere fi ni inu didun si iranti rẹ lọdọọdu ati pe, iṣẹ to ṣe yi ni Ọmọ-Ifẹ fi ma a nkan sara iyi nla si nipa oriki ti nwọn fi npe nibi gbogbo wipe:- Moremi Ajosọrọ, Ọlọwọ aremọ to fi ẹwa - ara ṣẹtẹ.
(Itumọ "Ṣẹtẹ" ni Ṣẹgun)

ỌDUN TUN DE

Mo fi itan yi kẹwọ lati kesi ẹnyin Ọmọ Ifẹ nipataki, igboro Eko wipe, asiko to lati ṣe iranti Mọremi gẹgẹbi a ti nṣe lati ọdun gbọrọ sẹhin. Nitotọ, Mọremi, ko laju afọju bẹni ko gbe arọ dide, ṣugbọn a ko le ri ninu Iwọ tabi emi ti o jẹ finu-fẹdọ fi Ọmọ kan ṣoṣo ti a bi rubọ fun agbaiye.

Mo tun nsọ ni a sọ yanju nihin wipe, iranti Mọremi lọdọdun ki iṣe Ẹbọ ṣiṣe, bẹni ki iṣe Oriṣa, ohun ti a le fi we, ni iranti ti awọn Krisitẹni nṣe fun ẹsun Jesu Krist ati bi awọn Musulumi ti ṣe iranti Irubọ ti Ọlọrun ni ki Anọbi Ibraimọ fi Ọmọ rẹ, rubọ, eyiti o nmu gbogbo Musulumi fi npa Agbo lọdọodun titi di oni oloni.

Bi Oluwa ba da ẹmi wa si iyoku di Ọsẹ ti mbọ.

# Ẹ ku ajọyọ iranti Ominira



Ni Oni Ọjọ Aje ti iṣe Ọjọ kini Oṣu kẹwa Ọdun yi, ni o di Ọdun meji ti Apapọ Naijiria gba Ominira, ti a si kuro labẹ Asia Ijọba Gẹẹsi.

Adupẹ lọwọ Ọlọrun Olodumare ti o dawa si di Ọjọ Oni larin gbogbo ewu ti o wa ninu Ọdun na, ti ko si jẹ ki a pade agbako. Gẹgẹbi Iwe Orin Dafidi ti wipe, "Kiki awọn ti emi ba pamọ nikan lo la yọ ninu ewu".

Ki Ọlọrun ki o ma a ṣe Olùdari awọn aṣiwaju wa, ki o si jẹ ki a ṣe Ọpọlọpọ Ọdun. Ẹ KU ỌDUN O.


# KERE O! AKIYESI PATAKI !!

Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, na wa na oni Gold Coast (Ankara) Ghana pelu, mẹfi re ko si ninu gbogbo oriṣiriṣi Egbogi kakiri Ilu Naijiria.




## Irohin kakiri Igboro Ilu Eko

Bẹ na ni ewẹ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lenu gbogbo tmla Comọde t'agba ni asiko yi ti nwọn si fi ṣe ọrọ ati orin larin aro wọn je nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS.

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ Ojulowo giriki ati atamaase fun iwosan "JẸDIJEDI" bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹna ni awọn le tun fi ọwọ soya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi Ifu, Igbẹ nse tabi aiko si igbọnsẹ deede, Inu rirun nigbakugba, ara wiwo, Esanri, Ehin didun, Oju sisan, tabi aiko riran kedere kokoro buruku lara, Osi inu Onigbameji ati oriṣiriṣi arun miran gbogbo pelu "Wipe" nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo E g b o g i LEOPILLS nitoripe a si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa aṣọ di ọtun patapata.

ṢE IRANTI PE ALAFIA L'OGUN ỌRỌ, IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9d)

**IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:-** Igo nla ṣile mẹfa abọ (6/6d) pere ni, Igo kekere ṣile mẹta abọ (3/6d) pere ni.

Bere Ojulowo Egbogi miran fun oriṣiriṣi Amodi ti o ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

**Waterloo Medicine Stores**
8. Palm Church Street, P. O. Box. 333. Lagos Nigeria Phone 22878, ati pẹlu ni Ṣọbu awọn arabinrin Mrs. C. O Babajide near Health office Ibadan ati ni A b i m b ọ la Medicine Store B29 Okesha Street Ilesha. Bisale Medicine Stores, British & Foreign Medicine (Dealer) S. W. 6/458 AGBOKOJO STREET, IBADAN N.

**AKIYESI:-** Ri daju gbamgba wipe Ṣọbu ti nwọn nta lo gbe raṣẹ lọ ra, bi bẹ kọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọ ta Adamọdi tabi oriṣi emiran fun ọ o, maṣe gba rara o.


# Ọpagun Naijiria




IRẸPỌ ATI OTITỌ

BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE TI WON NPE NI—

# RICHALET

FUN ARUN EJE ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yato patapata si awon Robi-robi Ije re lara enia o si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o bobuto ti o ba wa ni nu "EJE ARA" bi Monomono.

Meji re kosi nino gbogbo awon Egbogi ti nwon npe ni TONIKI Eje ti nwon si nta kakiri ni owo popku, adinugwo tabi ki o lo nile ko di owo. Iyen se a w o awa ki ta awon egbogi ba won yen rara tabi ti nwon npota ni Ile yi.

Gegebi awon Onibara wa ti mo irufe awon egbogi bawonyen a ma ba ojulowo egbogi atata ti araise fun tita lati awon ilu amani, Faranse, ati ti a w o n Tatambulu si Italije mo daju pe bi eje ara ko ba mo daradara awon amodi tabi silera wonyi le se o. Lakuregbe, orisirisi Inarun, Ojususu tabi didun, Jedijedi Ako-Iba, arun-Edoki, Aya didun Teopara ati Ekuru laya Ara riro, Lapalapa, Egbo-Ese Amodi Apo Ile ito, ehin didun tabi Ibaradi riro pelu. Egbogi Risalet a ma pa gbogbo kokoro buruku to wa n i n u eje ara patapata yio si fo eje re mo tonitoni pelu. Sa dan Igo re kan wo lara re dajudaju Iwo yio ma rohin re fun elominran p e l e igbakugba.

NIGERIAN MEDICINE STORES:
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE 20278.

**Waterloo Medicine Stores**
**Continental Medicine pecialist**
**8, Palm church Street, Lagos. P. O. Box 333,**
**Phone: 22878, Lagos Nigerian** (Oja ita Faji)

ADEDUN CHEMISTS,
48, WAKEMAN STREETPHONE 22878 YABA.

---

# THE IROHIN IMOLE

16, BAMGBOSE STREET, P. O. BOX 1495
**Phone 21985 Lagos.**

## Scale of Advertisement Rates

The following rates of Advertisement in IROHIN IMOLE are published for the benefit of our Advertisers & Readers.

## Display Advertisements

**Full page**

| | | |
|---|---|---|
| 1-12 | — | £38 0s |
| 13-26 | — | £36 0s |
| 27-52 | — | £35 0s |
| 52 Over | — | £34 0s |

**Half Page**

| | | |
|---|---|---|
| 1-12 | — | £20 0s |
| 13-26 | — | £19 0s |
| 27-52 | — | £18 0s |
| 52 Over | — | £17 0s |

**Front Page Solus**

| | | | |
|---|---|---|---|
| 1-12 | — | 12s | S.C.I. |
| 13-26 | — | 10s | „ |
| 27-52 | — | 8s | „ |
| 52 Over | — | 7s | „ |

**Run of Paper**

15s FLAT S. I. C.

## Nigerian Ports Authority

NOTICE OF INVITATION TO TENDER

CONSTRUCTIN OF SENIOR AND JUNIOR SERVICE QUARTERS AND VARIOUS SITE WORKS AT BONNY EASTERN REGION.

The Authority announces its intention to invite tenders for the following works at Bonny:-

SITE A - The construction of four quarters for use by Senior Service personnel, Generator house, Stewards and tradesmen's qaurters; Various site works including reclamation of part of the site, concrete road; water supply reticulation system; sewers and septic tank; pathways, perimeter fence and surface water drains.

SITE B - The construction of seven blocks of quarters for use by Junior Service personnel; five blocks of toilets (bucket type) various site works including reclamation.

Contractors who have the requisite experience, staff and plant to undertake these works are invited to apply to the Authority's Chief Engineer to be included in the list of those invited to t e n d e r. The application should be supported by evidence of the required experience, staff, plant and financial background. The Authority reserves the right to select a short list of Contractors to be invited to tender and will not enter into correspondence with any applicant not selected.

The closing date for application will be October 12th, 1962.

L. A. KUYINU
Ag. Secretary to the Authority.

N. P. A. NOTICE NO. 770.
25th September, 1962.

---

# YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 20-Feb 18) Iwo yio ri opolopo ogbon ko ninu ose yi sugbon isoro ni yio je fun o ati lo ogbon na fuora re.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Mase se imele ohun kohun ti o ba ni, ni sise, se lekan na nia da ako ko si i lati se.

ARIES (Mar 21 - Apl 19) Iwo yio ri idamu ninu ose yi, mase jeki okan re ni pare, Iwo yio si ri owo gba pelu.

TAURUS (Apl 20 - May 20) Gbogbo awon iyonu kekeke ti o ba yoja ni iwo yio bori won.

GEMINI (May 21 - June 20) Ire mbo fun o lose yi, bi o tile je wipe okan re ko sibi kan.

CANCER (June 21 - July 20) Ose yi yio dara fun o Ore re timo-timo kan yio ba o damoran, gba a, imoran rere ni.

LEO (July 21 - Aug 22) Gbogbo nkan lo su o, sugbon iwo 'io gbo Irohin ayo kan ninu ose yi.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22) Gbogbo nkan ni ara re yio ma a ya si lati se, Iwo yio si ni itelorun larin egbe ati ni bi se.

LIBRA (Sept 23 - Oct 22) Ara re yio lo tikotiko nipa ohun kan ti o nfe ti ko tete te o lowo iwo pelu obinrin kan yio lopo ninu ose yi.

SCORPIO (Oct 23 - Nov 22) Aiye ndara fun o lose yi, ni owo ati alafia, o dara fun o lati lo raja ni sobu.

SAGITTARIUS (Nov 22 - Dec 21) Ose yi miringindin fun o nipa ise ati nipa obinrin. Feso jaiye.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 19) Iwo yio ri idaru ninu ose yi, are okan yio si mu o, ose yi dara fun o lati kowe si okere.

# EYI NI AWỌN ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

## ỌJỌ AJE OCTOBER 1 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, Badagry |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowọ, Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Okun-Ọwa, Erunwọn Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikole |

## ỌJỌ IṢẸGUN OCTOBER 2 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege, Ebute-Ero, Ojo Ajido |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunlẹ, Idọgọ |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha-Ijẹbu, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejoro, Odo, Ibokun, Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi, Ifaki |

## ỌJỌ'RU OCTOBER 3 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Iberẹkodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode - Remọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilarọ, Oja - Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ OCTOBER 4 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun - Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imope Isara, Imodi, Ishan |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EIKTI | Egosi, Odo—Aiyedun |

## ỌJỌ ẸTI OCTOBER 5 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida, Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbowọ, Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Okun - Ọwa, Erunwọn, Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijoun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikole |

## ỌJỌ ABAMẸTA OCTOBER 6 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Agege, Ikẹja |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọla, Ajegunlẹ, Idọgọ |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ, Owode, Igbo-ọra |
| IJẸBU | Ibefun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹsha, Ijẹbu, Isara Imodi |
| IJẸSHA | Iwara, Ejoro, Odo, Ibokun, Ijẹbu,-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi, Ifaki, |

## ỌJỌ AIKU OCTOBER 7 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Iberẹkodo, Asu, Wasimi |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaosu, Ogere, Irolu, Itele, Ode - Remọ |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi - Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilarọ, Oja—Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ AJE OCTOBER 8 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹda, Babalokuta |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe, Ishan, Isara, Imodi |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Iloba, Imuroko, Erinmọ, Ilase, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado - Odo |
| EKITI | Egosi, Odo - Aiyedun |

# KA IROHIN KAKIRI AGBAIYE

*Lati ọwọ:— EJON'GBORO*

### EKO

Awọn akẹkọ mejidinlogota ni ile iwe Kings College Eko ti gba lati bere iwe ninu ile iwe wọn fun ọdun ti mbọ 1963.

### JAMANI

Ololá Alahaji Amadu Bello ti iṣe alakoso Ijọba Ipinlẹ ariwa ti ba ọkọ ofurufu gunlẹ si ilu yi lati ṣe ibẹwọ ọjọ meje ni ilu na. Yio si pada si eko ni ọjọ kẹrin oṣu yi.

### ABA

Adajọ ile ẹjọ giga kan ṣe idajọ pe ki ọdaran kan Okon Dick Misiody lọ fi pọnun marundinlọgọta (£55) tanran si kotu tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹrin, nitope o jẹbi ẹsun ole jija ti awọn Ọlọpa mu u fun pe o ji pọnun mejilelogoji ṣile mejila (£42 12s) ni ile iṣẹ rẹ.

### LỌNDỌNU

Jinnijinni da bo awọn ero marundinladọta ti o wa ninu Ọkọ Ofurufu ti o gbera pe on mbọ wa si Eko lati Lọndọnu, nigbati ọkan ninu awọn Injinni rẹ ko ṣiṣẹ mọ nigbati nwọn doke, Ọkọ na si bale ni alafia.

### NAIROBI

Ijọba Kẹnya ti ṣe ikede wipe gbogbo awọn Obinrin Kẹnya ni yio bẹrẹsi ma a san Owo Ori lati Ọdun ti mbọ yi

### EKO

Ijọba Apapọ Naijiria ti ṣe ikede wipe ẹnikẹni ko gbọdọ ṣe ipade ni igboro Eko ati agbegbe rẹ fun Oṣu meji.

### SHANNON IRISH

Ijọba ti ko enia mejidinladọta kuro ninu omi okun, nwọn si nwa enia mẹdogun nisisiyi ninu Ijamba ọkọ ofurufu kan ti o ja sinu omi.

### SWEDEN

Alakoso Ijọba Liberia, Ọgbẹni Tubman ati Iyawo rẹ ti de si ilẹ yi lati ṣe ibẹwọ ọjọ diẹ.

### ABẸOKUTA

Igba (200) awọn enia ni awọn alẹṣẹ ile-iṣẹ Gammon ni Abẹokuta ti da duro lẹnu iṣẹ, nwọn si sọ fun wọn wipe ko si iṣẹ mọ.

### KAMPALA

Awọn Ijọba ti bẹrẹsi ko awọn ẹlẹwọn jade lati ma a ṣe iṣẹ ariu ilu nitoripe awọn oṣiṣẹ Ijọba da iṣẹ silẹ nitori edeaiyede kan ti o wa latin [illegible].

### RODHESIA

Ijọba ti ko ọpọlọpọ awọn ọmọ Ogun si arin ilu nitori ija igboro ti o wa larin ilu na lati bi ọjọ mẹta.

### OWERRI

Adajọ ile ẹjọ giga Owerri ṣe idajọ pe ki ọdaran kan, Onyeama Ezeneri lọ san ogota pọnun (£60) si kotu tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu mẹta nitoripe o ṣẹṣi yinbọn pa ọmọ ilewe kan Okorie Abuchi.

### GABON

Enia mẹrin lo ku bamu bamu, Ogoji enia si fi ara pa ninu ija kan ti o ṣelẹ, nigbati awọn ara Kongo gba bọlu mẹta wọ'le, awọn ara Gabon si gba ọkan (3-1) wọ'le wọn.

### ROMU

Ọgbẹni Pandit Nehru, alakoso Ijọba India ti ba ọkọ ofurufu gunlẹ si ilẹ yi, lẹhin ibẹwọ rẹ ọjọ marun si ilẹ Naijiria.

## ỌKUNRIN KAN TI OJU ORUN DE OJU IKU

UGWU:- Jinnijinni ba gbogbo enia ni kutukutu owurọ ọjọ aiku ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu kẹsan ọdun yi, nigbati awọn ara ile r e t i atijade ọdọmọ kunrin kan, Gabriel Eduzor, ẹni ọdun merinlelogun ti nwọn k o si ri i, ni nwọn ba fi i p a si ilẹkun rẹ, nwọn si ba ti o ti ku hamubamu si o r i ibusun rẹ.

Awọn enia sọ fun onirohin wa wipe ko si nkankan ti o ṣe ọkunrin na k' o to sun ni alẹ ọjọ ti o tẹle ọjọ na

Awọn ọlọpa ti gbe oku rẹ lọ si ile iwosan lakulaku fun ayẹwo

## Nigerian Ports Authority

### PUBLIC NOTICE

**Independence Anniversary Celebrations**

CLOSURE OF PORTS

It is hereby notified for general information that ALL PORTS will be closed on Monday, 1st October, 1962, being a Public Holiday and that no port operations will take place on that day.

L. ADE. KUYINU
for: Secretary to the Authority

N. P. A. NOTICE NO. 769.
24th September, 1962.

## Ẹ KU'ABẸWO O!



EKO: Ọgbẹni Jawahurlal Nehru, alakoso Ijọba India, ba Ọkọ Ofurufu kuro ni Ikeja ni agogo meje kọja ogun iṣẹju ni irọlẹ Ọjọ Ọjọbọ ti iṣe Ọjọ kẹt-dinlogun Oṣu k ẹ s a n Ọdun yi, lẹhin ibẹwo Ọjọ marun si ilẹ Naijiria.

Ki Ọgbẹni Nehru to fi Naijiria silẹ, ni on ati Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa ti ṣe ibẹwo ile Naijiria ninu Ọkọ Ofurufu

Nwọn si fo yika ipinle mẹtẹta Naijiria ki nwọn o to pada si Ikeja ninu Ọkọ na.

Ki Ọgbẹni Nehru to fi ilẹ Naijiria silẹ ni o ti sọ wipe on fẹ ki Ọlọla Balewa ṣe ibẹwo wa si India. Ọlọla Balewa sọ wipe on gba ipe na, on yio si ṣe ibẹwo na lọjọ iwaju.

## IKEDE PATAKI

Itumọ-ala yio bẹrẹsi ma a jade lati ọsẹ ti mbọ ninu:

**Iwe Irohin Imọlẹ**

Iwọ ti o nla ala, ti o ko si mọ iru ohun to jẹ, ati nkan ti o le ṣẹlẹ si ọ; bẹrẹsi ma a ka IWE IROHIN IMỌLẸ lati ọsẹ ti mbọ. Iwọ yio si ma a ka oriṣiriṣi:-

**Itumọ Ala**

ninu rẹ.

OLOTU

## Akiyesi Pataki

Lẹhin ukan bi ọdun ẹfa sẹhin ti n w ọ n ko ṣe wa mọ rara, egbogi oju na tun wọ ilẹ yi. Bẹrẹ:—

## 'COLLYRIO PAGLIANO'

Bi amodi tabi aisan "OJU DIDUN" ba nyọ ọ lẹnu nigbakugba tabi fun ọjọ to ti pẹ jọjọ, yẹ ẸJẸ ARA RẸ WO" nipa lilo egbogi atata ti o daju fun ẹjẹ ara RICHALET Lẹhin na ẹwẹ, ki o si ra egbogi ti awọn ara ilu Tatambulu (Italy) ṣe lati ma a kan si oju na pẹlu, ti a npe ni "COLLYRIO PAGLIANO" fun oju didun, Meji rẹ ko si ni igboro ilu Naijiria.

Ṣe iranti wipe oju ni baba ara o, ijafara si lewu pẹlu.

Bere ni Ṣọbu awọn Olori egbogi Jamani igboro ilu Eko, ti nwọn npe ni:—

**Waterloo Medicine Stores**
**Continental Medicine Specialist**
**8, Palm church Street, Lagos. P. O. Box 333,**
**Phone: 22878, Lagos Nigerian.** (Ọja ita Faji)

## Nigerian Ports Authority

ELECTION OF MEMBERS TO REPRESENT THE PAYERS OF SHIPS' DUES AND THE PAYERS OF HARBOUR DUES HELD ON THE 21ST DAY OF SEPTEMBER, 1962.

NOTICE IS HEREBY GIVEN that in accordance with the provisions of the Nigerian Ports Authority (Election) Regulations 1956 the under-mentioned candidates have this daybeenduly elected as Members of the Authority to represent the payers of Ships' Dues and the payers of Harbour Dues with effect from 23rd September, 1962.

MEMBERS TO REPRESENT THE P·YERS ·F SHIPS' DUES:

Chief Kol·wole Balogun
Chief Shafi Lawal Edu
William Jesson Joyce Esq.

MEMBERS TO REPRESENT THE PAYERS OF HARBOUR DUES:

David Fleming, Esq.
Williams Geoffrey Ducan, Esq.
Alhaji Shittu Ade. Fashola.

L. ADE. KUYINU
Returning Officer

21th September, 1962.
N. P. A. NOTICE NO. 768.

*Printed and Published by MOD'IPE PRINITNG PRESS 16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495, Phone 21985, Lagos Olootu: E. A. Adeniji 24, Oliyide Street, Odu—Abore Mushin.*